# EKO AKETE

## IWE IROHIN OSOSE.

VOL. II. NO. 58. SATURDAY, AUGUST 18, 1923. FOURPENCE.


Mundlos on top Mundlos.

## A. KESSLER,

GERMAN HAMBURG

Iwọ le ranṣẹ Ẹrọ-Iranṣọ "*Mundlos*," "*Adler*" ati Ẹrọ-riran bata ni 7, Labinjo Lane.


CHIEF SECRETARY'S OFFICE
15 AUG. 1923









A nranṣẹ orisirisi ọja fun enia to tete nlọ nilẹ ni *Nigeria*.
A si nta Chun ẹrọ orin, Awo-Abọmafọ, Kẹkẹ-ologere, Waji.
Ẹ le ri ra lọdọ J. S. Johnson, Alhaji Masu, ati H. Campos, ti Campbell Street.


Mundlos on top Mundlos.


## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware Beer. Wine. Iron Bedsteads Ruley Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes. Sewing Machines. Champagne. Cement, Biscuits in cases Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons. Piano. Padlocks, Beads etc., etc., etc."**

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN

IBUSUN-ILESANMI ati MASINI-A-NJUWON.

Ọgbẹni DURO THOMAS

Onisowo-towolaw, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to ṣeṣẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni ile Ọja rẹ 55, Ita Mase leti ita Faji, l'Eko.

Ifa mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwon nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Awúre nyin pade nibẹ.

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ikole fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọọ.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni 374. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## *Lagos Ekitiparapo Society.*

*Patron*: HIS HIGHNESS

THE OWA OF ILESHA.

The Council of the above Society respectfully request all Ekiti and Ijesha Children (Male and Female) who at present are not members of the above Society to register their names personally or by letter at the Office of the Society,

***Arapa Hall,***

Williams Street, The Secretary will be in attendance from 8 to 12 noon and 2 to 5 p.m. until 31st of August, 1923.

OGUNTOLA SAPARA,

*President.*

---

## *Mr. B. O. Joseph.*

of 64, Breadfruit Street, Lagos, begs to inform the Public that he is now a free Commission Agent, and he is now prepared to sell any kind of goods on behalf of any firm.

*21 years' experience in trade.*

**Cotton.**

**Sundries.**

**Hardware.**

**Provisions.**

*Business Place* :—

20, Balogun & Breadfruit Streets, Lagos.

---

## Wanted to Purchase.

Handel's "Halleluiah Chorus" and "Coronation Anthem" in Gramophone Records.

*Reply to The Editor.*

---

**TO LET**

*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

L'AIF'ỌTA PE.

Agbayanu ni Ipade Nla ti awọn Ẹgbẹ gbogbo Ilu Nigeria *(Nigerian National Democratic Party)* ṣe ni Ile Afari-Ogun ni *Saturday* ọsẹ to kọja; Irohin ko-to-af'ojuba ni; ọrọ npe ọrọ ranṣẹ ohun ti o si jẹ akọtun ninu Ipade na ni obinrin kan ti a npe ni Rekia ti ẹnikeji rẹ tẹle, ti o sọrọ fun apa ti awọn ẹgbẹ rẹ, eyiti Erelu jẹ Olori wọn; ka-si-nkan l'ọrọ arabinrin yi, o kun fun iṣiri lọpọlọpọ tobẹ ti gbogbo Ijọ fi kan sara si i, nigbati o bu ọrọ sọ; ninu gbogbo Ipade irufẹ eyi ti awọn ẹlomiran ti nṣe bọ eyiti a si ti nlọ ko iti si igba ti awọn obinrin wa sibẹ ri a nbọsi-bọsi pe ki nwọn sọrọ, bikoṣe inu Ipade ti Ilu *Nigeria* yi; iyoku iregbe nigbati o nlọ si agogo mẹjọ alẹ ti adun na pọju, Alaga fi ofin si Ipade lojiji, a si ri bi gbogbo ọmọ ẹgbẹ to wa na—nwọn le ni ẹgbẹfa enia—ti nfa tikọ lati tuka lọ sile, Oloye Oluwa fọ'gi ninu ọrọ rẹ ni alẹ ọjọ na bẹ si ni Ọgbẹni T. H. Jackson ati Ọgbẹni S. Duncan pẹlu. A ko le ṣẹṣẹ ma sọ ọrọ ti Baba Ẹgbẹ na Ọgbẹni J. Egerton Shyngle sọ mọ.

RE WA O, AJILO-BI-OJE.

Adele Ọba Sir Donald Cameroon K.B.E., C.M.G. dakan lọ bojuto iṣẹ Ijọba l'ọna Oke laipẹ, yio si pada wa'le, ni'wọn ọsẹ meji.

ỌMỌ-ONIKU, Ẹ KABỌ.

Kosibotiri ni irohin ti a gbọ nipa ti sisin ti a sin aburo Ọgbẹni A. W. Thomas ti a sọrọ iku rẹ sinu Iwe-irohin yi ni ọsẹ to kọja. Ọgbẹni ti o ṣ'alaisi na jẹ baba awọn arakọnrin wa Joseph Belo Thomas ti o nṣiṣẹ ni Ile Igbimọ Ilu (*Lagos Town Council*) ati Daniel O. Thomas ati awọn ọmọ rẹ miran. A gbọ pe nigbati a tu ọfọ yi fun Alafin, lọgan o paṣẹ ki a da gbogbo Ilu ti nbẹ ni'lu duro, o si kẹdun Ologbe lọpọlọpọ; l'oriṣi-riṣi ọna, nigbati a si fẹ sin oku, gbogbo Ilu lo pe biba gidipã awọn Musulumi, nitori Imale ni Ologbe nṣe; a si sọ pe Lemọmu Agba ni Ọyọ lo ki'run si oku l'ara ki o to wọ'lẹ; lẹhin eyi ọgọrọ ni awọn enia to lọ ba Alafin daro ọfọ iyekan rẹ yi, ati awọn ọmọ oniku papa; awọn Alufa ti Ijọ awọn Onigbagbọ si wa si'bi oku na, a si gbọ pe nwọn ṣe bi o ti tọ pẹlu.

Owo ti a si sọ pe awọn Ọgbẹni Joseph Belo Thomas na ati aburo rẹ Daniel O. Thomas l'aikan ti Ọgbẹni J. Mọṣalewa Thomas sibi oku yi ko ni'ye, bẹ na si ni Alafin ṣe bi arira nipa fifi ohun jijẹ, mimu, su gbogbo awọn to wa ki i ni Afin. A si sọ pe awọn Oloye ati awọn Olorukọ ni ode Ọyọ ko ku nibi oku na.

Awọn Arabinrin wa Mrs. V. Mokolu, Mrs. L. West ati Mrs. A. Taylor ti nwọn jẹ ẹbi (*Cousins*) Ologbe na wa si ibi oku yi pẹlu.

AMI AGBELEBU L'ARA KẸTẸKẸTẸ, EYI ARA!!!

Ni *Sunday* t'okọja ọrẹ wa Alagba kan sọ pe, nigbati Alufa A. B. Akinyẹle B.A. Ọga-Agba *Grammar School* ti Ibadan fi wasu Isin Ikore ni *Church* St. Peter nibi laipẹ yi, o ni o sọ pe boya ami Agbelebu ti o nbẹ l'ara Kẹtẹkẹtẹ ti Jesu gun lọ si Jerusalem nijọ kinni l'o mu Olukọni Nla

na sọ pe ki nwọn lọ fa a wa fun on, a sọ pe oniwasu na ni lati igbana ni gbogbo kętękętę ti ni ami Agbelebu l'ara, o ni ko si kętękętę kan ti a o ri, ti ki yio si ami yi l'ara rę; ọrọ yi ya wa l'ẹnu nigbati a gbọ, a si fi s'ọkan; ṣugbọn ni *Tuesday* ọsẹ yi, iyanu wa tubọ pọ gidigidi nigbati a ri kętękętę kan ni igboro ti o nję l'ọna Ṣabu awọn Ọlọpa ni Ita Tinubu lati lọ si ti Ọgbęni J. A. Sule; l'ọgan, a ranti ọrọ ọrę wa yi, bę si ni a ta 'ju kan lati wo ara kętękętę yi. Ki l'a ri? Ohun ti a ri si ni ami Agbelebu; ọkan wa ni ogoro-ęhin kętękętę yi, ekeji si dubu rę ni apa iha ibi ori rę!!!

Wo mi na ęnikeji, a da kękę ologere ti a gun duro, a si wo Ami yi ni awofin pęlu iyanu nla: ko yę ki a maṣe rohin nkan abami yi fun awọn ọkawe wa: ni gasikia, Awamaridi ni Iṣę Olodumare. To to fun un!!!

### IPADE NBĘ.

Ipade gbogbo-gbo ti Ęgbę *Nigeria* nbę l'ọsan yi ni 'bi kanna li akoko kanna, a tanma pe gbogbo ęsę awọn ọmọ Ęgbę yio pe sibę perepere.

### ARA LILE NI 'PĘKUN ỌRỌ.

A gbọ pe Ọgbęni wa A. W. Thomas gba ọlọfę lọ si ọna Duala fun ilera lęhin igbati o ti san ninu amodi rę ni oṣu diẹ sęhin. Ajinde ara a ma jẹ ọ, ọmọ oṣarẹwa-ṣakin!!!

---

### IBADAN AND OYO-NEWS AND NOTES.

*[ From our Correspondent. ]*

Death of Durojaiye Ishola Thomas, the Balogun, Igbimo Alafin, otherwise known as Oyo Mesi, at his residence Agunpopo on Thursday the 2nd August 1923.

The funeral took place on Friday 3rd August 1923 in the presence of his children, Messrs Joseph B. Thomas, Sanitary Inspector, and Daniel O. Thomas, Licensed Customs Agent, who have come up from Lagos a few days before the sad event amidst an overwhelming crowd of people both Christians, Mohammedans and Pagans. Conspicuous of those who attended the funeral ceremonies were the following:—

The representatives of the Alafin, the Aremo, Prince Sanusi Oladigbolu, the Bashorun, Ashipa, Otun-Efa, Osi-Efa, Ono-Efa, Alapini, Onosokun, Agunpopo, Ilugbenka, Tijani, Alfa Gboro, Iya Alagbon, Iya-Ori, Iya-Lagure Saiyero, Laguno, Baba-Iyagi, Oyin-Ayaba, Ilusinmi, Kudefu, the Revd: S. A. Sodipe C.M.S. Agunpopo Church, Mr. S. I. Taiwo, Dispenser of Baptist Dispensary, Oke Isokun, Mr. S. M. Akidele, the Alafin's confidential Clerk and Mr. Edwin Cole, personal clerk to Captain Ross, the Resident of Oyo.

The deceased Balogun has suffered for a very long period from certain protracted illness. He is a younger brother of that popular Auctioneer, Mr. Andrew Thomas of the Palatial Buildings 85, Odunfa Street, Lagos, and also first Cousin of H.H. Oladigbolu, C.M.G. the Alafin of Oyo. And both have lost a loving and respectable member of the family and a sound councillor by his death. To the Alafin and Mr. Andrew Thomas we tender our sincere sympathy.

On Tuesday 6th August 1923 the Funeral Obsequies and feasting were observed according to customs by the Alafin and no less than 300 guests were present and entertained at the Palace. Several Cows having been killed a day or two before, feasting and drinking continued till midnight. Various kinds of Drums were at play and dancing was indulged in by all and sundry including the Christian Ladies and Gentlemen to the strain of Native airs. Conspicuous of those present at the Palace were Mrs. Victoria Mokolu, Mrs Layinka West, Comfort Agbe, Ashiyanbola Taylor, Adeyemi Green, Henrietta Alakija, Messrs J. Omosalewa Thomas, J. B. Thomas, Dan. O. Thomas, and Bankole Thomas all from Lagos.

At Ibadan Station on Friday 10th August 1923 one Constable No. 269 stopped the Alafin's car out of sheer grudge or previous animosity against the Driver, and without any just cause. The car contained passengers, (the Thomas's family) from Oyo. The matter was brought before the Police Commissioner, Mr. Nolans; the Constable failed to give satisfactory explanations or reasons for his misbehaviour for he was very rude to the passengers consisting chiefly of women and children. He also displayed high temper, obstinacy and disobedience at the decision of his superior Officers, he was reduced to lower grade. This will certainly serve as an example to those foolish set of Constables one generally meets about up-country. Commissioner Nolans is an Officer of great experience and deserves our special praise.

*The New Legislative Council of Nigeria.* It is the opinion of all the educated people at Ibadan and Oyo that in Mr. Andrew W. Thomas we have a fit and proper person to represent our country. Others as experienced and capable consist chiefly of Priests in Holy Orders who should not meddle with politics.

---

### OLD GRAMMARIAN SPORTS SECTION.

DEAR SIR,

There will be a **GENERAL MEETING** of the above Section at the Grammar School Hall on Friday next 24th instant at 5.30 p.m. prompt. Old Boys who are interested in Sport, and have not enrolled their names as members are also cordially invited to attend.

**AGENDA.**

1. PRACTICES.
2. ARRANGEMENTS FOR FIXTURES.
3. GENERAL.

Yours sincerely,
GEO. I. PHILLIPS,
*(Hon Sec. Sports Section)*

## ABẸOKUTA.

A ṣe isin Iranti fun Dosunmu, Ọba Olowu, ti o w'aja, ni Ile-isin Ijọ Ọmọ-ibilẹ, ni Ago-Owu, ni Sunday to kọja, ni agogo mẹta.

Alufa N. A. Ọnatolu ṣe iwasu to kun fun ọrọ iṣiri nipa itẹ ati ãyan Ọba Dosunmu fun ohun to kan ti Ọlọrun. *Ki Ọba k'o pẹ!*

Ẹnikẹni ti o ni itẹ rere si ilu rẹ, ti o ba lọ si Abẹọkuta, ti o rin ilu yika, ti o si ṣe akiyesi ãfin awọn Ọba wa ko le ṣe alai mi ori, fun ipo ailẹyẹ ti nwọn wa.

Ilu papa kun fun ahoro, àlàpa ati ọhun bẹ, ọpọlọpọ li o wá iṣẹ lọ si oko; ati jẹun, ọtọtọ ọran sa ni. Nipa ti Ita (*Streets*), "Oke rẹ, gẹgẹle rẹ," ni bi orin Ọya. A ni ireti ṣa pe iṣẹ rere eyiti Alake ati awọn Igbimọ rẹ ti bẹrẹ nipa Titi (*Streets*), ki yio duro. Olowo li o sa nsọ oke di ilẹ.

Inu wa dun, ori wa si ṣi nigbati a ri iṣẹ ile Pẹtẹsi ti Ọba Ọṣilẹ nṣe lọwọ larin ãfin rẹ; a ti mọ ile na pari, a si ti bo panu rẹ: ki a rẹ ẹ li ẹfun, ki a si kun u li ọda li o ku; lẹhinna ki nkan wa ṣe ẹnu 're. Eyi nikan kọ; Ọṣilẹ wo gbogbo ile awọn Olori ni ẹkule, o si ntun wọn kọ. A ṣe abẹre pe, bi owo ilu li o fi nkọ ile na, tabi iranlọwọ ti ọdọ ẹlomiran wa ni? Esi si wa pe, owo ilu kọ, iranlọwọ tọrọ ko si ti ode wa; owo apo on ni on nlo. Eyi wu wa lori pupọ. Ki Ọlọrun ki O jẹ ki ipari ile na ṣ'oju ẹmí, ki ẹmí Ọba si gun lati lo ile na lọ titi. *Amin.*

ABOGUNLOKO.

## Open Letters.

TO CELEBRITIES, NOTORITIES, ETC., IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

No. 29.

To

MR SAMUEL H. BRAITHWAITE,
Editor, *Nigerian Advocate*,
38, Bridge Street,
Lagos.

Impertinent Newsmonger,

Greatly surprised am I to find that no sooner your paper began to see the light of day—a little over a fortnight ago—than it considers itself strong and competent enough to pass hasty judgment on other journals in town already existing and doing their bit *long before* the appearance of your RAG. (See Page 3 of your issue of the 8th instant.)

Without taking the least pains to study the principles for which these papers stand, and to which *The Nigerian Advocate* is as blind as the bat, it at once plunged headlong into their irrational analysis, thus making itself NOTORIOUS and A PUBLIC NUISANCE at that !!!

Is your organ A Foeman worthy of the Steel ?

*Ne Sutor Ultra Crepidam !*

EKO AKETE.

## KINI A NPE NI ORILẸ-EDE.

Lati ọwọ ADELANI GBOGBOADE.

Lati igbati iwa ti ṣẹ ni a ti ri pe Ọlọrun da orun on aiye, ati ohun gbogbo ti o wa ninu wọn. O da ogunlọgọ enia, ẹranko, ẹiyẹ ati ẹja sinu aiye. O fi onikaluku awọn ẹda wọnyi sọtọ si ibi kọkan pataki lati ma gbe, ti a mọ loni bi ilu awọn enia, igbo awọn ẹranko, itẹ awọn ẹiyẹ ati ibu awọn ẹja. O fi awọn kan sọtọ si ibiti o moru pupọ fun ibugbe, awọn omiran si ibiti o tutu, awọn omiran ẹwẹ si ibiti o tutu pupọ.

Olukuluku awọn ẹda wọnyi a ma fi ibugbe wọn tãka si ara wọn, ohun ti a ba sa ni li a tãka. Nwọn a si ma fi nani gẹgẹ bi a ti ma ngbọ nigba gbogbo pe—ilu temi dara ju tirẹ lọ; a si fẹran lati ma pe awọn ti ki iṣe ara ilu tiwa ni ara ilu-ki-'lu. Iṣe enia sa ni iṣe ẹranko, mo ro pe bakanna ni yio ri larin awọn ẹranko ati ẹiyẹ, boya awọn ẹja le ma hu irutẹ iwa bayi pẹlu—Ẹlẹda lo sa mọ ohun ti nwọn nṣe ni abẹ omi.

Ko si ohun meji ti o mu ero bayi wa si ọkan ọmọ enia ati awọn ẹda yoku, bikoṣe eto ti a ba ni ode aiye, eyini ni aidọgba ti o wa larin ipin ti Ẹlẹda pin fun olukuluku wọn, titi awọn to pọ si ngun won loju—ohun ẹni ni sa jọ ni loju.

Nigbati a tun boju wo ode aiye lọ gãràga, a ri pe oniruru awọ ni Ẹlẹda da si ara awọn enia, ẹranko, ẹiyẹ ati ẹja; àwọ awọn apakan dudu, ti awọn kan funfun, ti awọn omiran pupa, ti awọn omiran ẹwẹ si jẹ oféfe. Bakanna ni a ri i larin eweko igbẹ, ti apakan tutu yọyọ, ti awọn ododo nfi ogo oriṣiriṣi awọ won han. Ki nṣe ninu awọ ara nikan ni ẹda yatọ si ara wọn—ede ti nwọn nfọ yatọ pupọ si ara wọn pẹlu, ti a ba yọ igi inu igbo ati awọn ẹja inu omi kuro, boya ẹwẹ, awọn wọnyi na yio ni ọna ti nwọn fi nba ara won sọrọ.

A o sa le fi oru han, oniruru ede li a ri larin awa enia dudu, gẹgẹ bi a ti ngbọ ni ẹnu ara wa kakiri gbogbo ilẹ wa. Bakanna gan lo wa larin awọn enia funfun, pupa tabi oféfe. Ede ẹnu awọn ẹranko yatọ si ara wọn, bẹ si ni ohun orin ti awọn ẹiyẹ oju ọrun nkọ yatọ leti si ara wọn. Ki isi nṣe bayi nikan, iwa ati iṣe oniruru ni a ba lọwọ awọn ẹda—gẹgẹ bi ti awa enia dudu ti pẹka si pe ọna ainiye—ni oriṣiriṣi ọkan-ko-j'ọkan, bakanna gan li o ri larin awọn enia funfun, pupa tabi oféfe. Iwa awọn ẹranko igbẹ yatọ si ara wọn, bẹ si ni ti awọn ẹiyẹ oju ọrun, a si le ro pe bakanna ni ti awọn ẹja inu omi yio yatọ si ara wọn, bi o tilẹ ti jẹ pe ti awọn ẹja ko le da ni loju lati so danyin-danyin—nitoripe ibugbe wọn jinna si wa.

Bayi ni a ri ipin ti Ęlęda pin fun onikaluku ęda Rę ni ode aiye, ni orişirişi okan-ko-j'okan, titi ęnikini fi yatọ si ti ęnikeji—ko si ba ara wọn mu. Aiba ara wọn mu ninu ohun gbogbo yi gan ni o mu ki awọn ęda, lairo o jinlę pe awọn ki işe ọkanna, niwọn igbati nwọn ko ti da wọn si ori ilę kanna. Nwọn gbagbe pe Ọlọrun, Okanşoşo na ni Ęlęda ohun gbogbo, ati pe ọmọ-iya si ni gbogbo ęda ję.

[ *Koi ti pari.* ]

## *EKO AKETE.*

EKO, SATURDAY, AUGUST 18, 1923.

### AILOWO L'OWỌ BABA IJAYA.

TABI

### EWU ỌJA KIKIRI FUN AWỌN ỌMỌDE BIRIN WA.

Ki iya ọmọ gbe ọja—pãpã ohun ti ęnu-nję—le ọmọ rę obirin l'ori lọ ta kakiri igboro, ki şe ohun t'o ni ẽwọ̀, nipa bayi, awọn ọmọ-binrin ję iranlọwọ kan pataki fun iya wọn; nitori awọn iya wọn kò ni şai ni bi ẽlo kan lọwọ fun ati gbọ bùkátà ile, bi emi ni rira-ohun wẹ́wẹ̀wẹ́ sile tabi sisan owo *School* tabi rira iwe *School* fun irufę ọmọ bẽ, ki baba to gba owo oşu nibi 'şę tabi ki baba miran ti ki işe işę oşu to ri owo fi silę ninu eyiti yio fi da gbogbo owo ti iya na ti na lọna bayi pada fun u.

Ęwè, ki ọmọde mã ta ọja, pãpã ọmọbinrin, yio tete fun irufę ọmọ bẽ ni lãkàyè mímọ owo-şiro eyi pęlu yio si tubọ ran ọmọ na lọwọ ninu ẹ̀kọ́ rẹ̀ ni Ile-iwe, tabi ti ọmọ na ko ba nlọ si Ile-iwe, kikiri-ọja yio tete jęki irufę ọmọde-binrin bẽ ni ifę ati ọgbọn ọ̀wọ̀ şişe, nipa pe ki o mọ sisọ õkan di ẽji bi o ba ti ndagba si i.

Nigbamiran ti awọn ọmọ wọnyi ko ba tà, o ję àşa pupọ iya lati mã nà wọn ati lati mã bú wọn ni "àpà-àmùşùà, amumi-mu'ràwé" ati irufę ọ̀rọ̀ bawọnni, ọmọ ti a bú l'oni bú l'ọla, ti a si nşi l'ábàrá pęlu, yio wá wọ̀rọ̀kọ̀ fi ş'adá lati wa ọna miran lati tà ki on le ma bọ lọwọ ẽbú ati inà (ko şa ni ba ara rę ra a, a mọ pe awọn ọmọ miran wà ti nwọn nşere nigbati nwọn ba nkiri) afara ko si, ti ọmọde yi ba gbe ọja rę, o di k'o fi ori le ile awọn Şękiri ati ile awọn Kurumọngbọ, ki ni oku ti nwa bikoşe agọ̀? Agbare-gbabọ ibi t'o nlọ na nipe lęhin igbati awọn enia wọnyi ba ti hu ọmọde-binrin nã ni iwa iwọsi tan ti o si gba owo ti o kọja iye ọja rẹ̀ ti o si şẹ̀kù pęlu, o di ki o da ọja rẹ̀ nu ki o si dori kọ̀ná ile pęlu ayọ fẹ̀rẹ̀ pe on ti tà tán; iya rę nã ti ko mọ̀ kan lọgan ti o ba ti f'oju kan owo ti ọmọ na gba lọna bayi, yio bẹ̀rẹ̀ si ki ọmọde yi męsan męwa, o mã gbọ "õku ọmọ ajógbẹ̀ru má jó gbękọ o şe ọkọ mi." A kole sọ ọpọlọpọ awọn ọmọdebinrin ti awọn enia wọnyi tabi awọn elomiran ti baję l'ọna yi; lalai ję pe awọn iya awọn ọmọ na mọ ibiti ibọn ndun. Ninu ọsę yi a pariwo le awọn ọmọdebirin kan ni ọna Odo Oluşi ni apa ile Aya Adu nibiti Ęrọ Omi Ilo wọlẹ̀ şinşin l'apa ibi irà ti Ọba nkun nisisiyi ki ni nwọn şe? A gbọ pe o ję àşà awọn ọmọ na lati ma da ọja tita wọn bi mọin-mọin, Ęja dindin, Gãri, Ępà, ati nkan miran nù nwọn a si tọ awọn Ibiobio ti a gbọ pe Ọgbęni kan ti o haya ile nibę ti gba awọn enia wọnyi l'aye lati ma wa pade awọn ọmọ yi nibę; lęhin igbati nwọn ba si ti hu iwa ibaję pęlu awọn ọmọ na tan, a gbọ pe o ję àşà Ọgbęni na ti o ni on nran Maşĩnni lati ma gba tọrọtọrọ "kọmişọn" rę lọwọ awọn ọkunrin pà-npà-pá-npá wọnyi.

A sọ ti Wundia kan ti ęnikan fę s'ọna pe o nkęgbę wa sibi ti a wi yi, l'ọgan, şe bi "Awo ti nlu ni Awo njo," bęni awọn kan lọ tę ęniti o nfę ọmọ na l'ęsę ęhin, iyoku iregbe nigbati ọmọde-binrin yi tun wa sibę, bi o ti wọ'le tọ awọn Ida-nfo wọnyi lọ, lęhin igbati o ti da ohun ti o nta nu tan bęni ọkọ rę yi si rọra wọ'le de to mu ni m'ọwọ m'ọrun, itiju ọjọ na fun ọmọde yi ko şe fi ęnu sọ.

Ọkunrin Agbawo kan ti o nşe iru "işę" bayi ti a si rohin rę sinu Iwe-irohin yi ni ọsę dię s'ęhin, lọ si ęwọn oşu męta nibi pęlu işę aşegan. A si fę ki awọn ọtęlęmuyẹn doşiri ka ibi ti a juwe yi lati f'opin si jamba na.

Ejọ ki agbalagba giodo-giodo mã ba awọn ọmọdebinrin kekeke jẹ l'o wọpọ ni Kõtu nisinsinyi; yio si jẹ didun inu wa bi awọn Ọpa Ọba ba ji giri lati tẹ irufẹ ibajẹ yi pa.

Ẹnyin Õbí ati Alágbàtọ́ ọmọbinrin, ọrọ yi d'ọwọ nyin o.

Gbõngbõn kan kò si, afi ẹnit'o ba nti ara rẹ !!!

## ORIN NI OHUN ILẸ WA.

Bi a ba ṣakiyesi ọkan ninu orin ilẹ wa fun iwasu ni igboro ilu, ninu eyiti a fi ṣe ẹkún iwe orin ti Ijọ C.M.S. ikarun (No. 5.) a o ri i wipe a ko le kọ ẹsẹ mẹtẹta lalai yi ohun orin (*Musical note*) diẹ pada ki o le ba awọn ọrọ orin na mu dede (*rhythmically i.e. movement in the succession of sound*).

Ila kini ti ẹsẹ kini lọ bayi :—

Ọ—ba a ba kẹ a—wa o kẹ.

*m: m: d | s: s:-/d m: d | s:—:—‖*

Ila kini ti ẹsẹ kẹta lọ bayi :—

Ẹ—mí o—ti—tọ a—wa o ni.

*d: s: d | s: s:-/d: m: d | s:—:—‖*

A o ri wipe ohun orin (*musical notes*) meji ti o bẹrẹ ẹsẹ kini yatọ si ohun orin meji ti o bẹrẹ ẹsẹ kẹta; eyi jẹ apa kan aidọgba ti mo ntọka si, ti o si nfẹ atunṣe.

Inu mi dun lati ri ipa ti ẹgbẹ *African Church Choir Union* nsa fun atunṣe orin ni ohun ilẹ wa, mo si tun yọ bakanna lati gbọ pe Ijọ enia dudu (*The African Church*) ni Ajọ Igbimọ nla (*Conference*) ti nwọn ṣe kọja, daba lati yan Igbimọ kekere kan ti yio ma bẹ awọn orin ni ohun ilẹ wa wo fun atunṣe. Adura mi ni pe ki Oluwa ma ṣai ran awọn ẹgbẹ wọnyi lọwọ fun idagbasoke wa gẹgẹ bi orilẹ-ede. *Aṣẹ.*

Iru ihin bayi ki mi l'aiya lati ma ba iṣẹ mi bọ ninu iwe-irohin nipa orin ni ohun ilẹ wa lalai kọmi'nu si ọrọ ti ẹnikan ti o pe ara rẹ ni "A. Ọla. Ajib;" sọ si mi ninu iwe-irohin "EKO AKETE" ti ọjọ keje oṣu July, 1923, ati eyiti o sọ ṣaju akoko na. Ọpọ awọn ti o nka iwe yi le ma f'oju s'ọna wo iru idahun ti ngo fun ẹniti o kọ iwe na; mo fẹ sọ fun awọn ẹni bẹ wipe—"Ẹ MA WO 'BẸ." nitoripe aniyan ti mo fi nsọrọ nipa orin ni ohun ilẹ wa yatọ si iru ọkan ti oluwarẹ gunle lati sọ iru ọrọ ti o t'ẹnu rẹ jade si mi. Ẹnikẹni ti o ba nfi lakaye pẹlu suru tẹle mi yio le jẹri wipe nko sọrọ gẹgẹ bi ara ijọ kan, bẹni nko si gbe ijọ kan pọn lati fi ṣata ijọ miran.

Bi a ba ri olohun-iyọ ninu Ijọ miran ti nwọn nfi ebu pa enia l'ara lai ṣ'osun, njẹ nipa eso wọn li awa yio fi mọ wọn.

Ṣugbọn "Bi ẹni abinibi ba huwa egun Ọlọrun la fi fun."

Nitorina lati isisiyilọ nko ni ṣe iyọnu lati gb'ẹnu le ohunkohun ti oluwa rẹ ba tun sọ l'ori ọrọ mi nipa orin ni ohun ilẹ wa.

OYENẸYẸ.

## BRITISH EMPIRE EXHIBITION (1924.)

Prizes of £3. 3. 0. each are offered for the best example of each of the following native industries :—

| | |
|---|---|
| Carving | Silver Work |
| Leather Work | Metal Work other than Brass or Silver |
| Native Mat | Pottery |
| Baskets | Bead Work |
| Brass Work | Native Cloth |

Each article accepted will be purchased at its market value, each prize-winner receiving the £3. 3. 0. in addition.

All exhibits should reach the Exhibition Commissioner in Lagos not later than October 15th 1923, and not as previously announced.

## UNION OF YOUNG NIGERIANS.

**Names of members of Executive Committee.**

*Official:—*

Dr. Moses J. da Rocha M.B., C.H.B., (*President*)

" J. C. Vaughan M.B., C.H.B., D.T.M., (*Chairman*)

J. Rosiji Turton *Treasurer.*

C. B. Olumuyiwa } *Auditors.*
A. B. Laotan }

Ayodele Williams, *Barrister-at-Law.* }
Mr. Georgius Cole, } *Secretaries.*
" A. J. Marinho, (*Jnr.*) }
" Shodeinde. }

*Unofficial:—*

Councillor O. Alakija, *Barrister-at-Law.*

| | | | |
|---|---|---|---|
| Mr. | O. A. Omololu, | Mr. | Tiamiyu Savage, |
| " | E. A. Akitan, | " | I. J. O. Soyode, |
| " | G. C. Johnson, | " | A. I. Yakub, |
| " | A. Sagbemi Abisogun, | " | Oluyele Bright, |
| " | C. A. J. Williams, | " | Fajumobi, |
| " | Agbabiaka, | " | G. K. Gomez. |

### IGBẸ L' OWO WÀ.

LAGOS—Ekuro.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.
Cooperative Wholesale Society Ltd.,
Jurgens Colonial Product.

£11 10—£12 10 fun *ton* kan.

Epo.

£23 10—£25 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

Cocoa.

£24—£26 fun *ton* kan bakanna.

KANO—Competitive Prices

Ground Nut—

Skins 1/10½ per lb, Hides 4½d per lb

### POSI T'O JIRE.

Ẹnikẹni le ri awọn Posi alarabara ti a ti ṣe lọṣọ lati Ilu Ọba wa ra ni ile ọja Kọlade ni 40A Joseph Street, Okepopo, ati ni No. 1, Moloney Bridge St., Anikantamọ; Ọtọtọ ni iye owo wọn, lati £6. 6. titti de 25 guineas. Aṣọ oku (*Shroud*) Yọmini to funfun bi lekeleke si wa nibẹ fun tita pẹlu.

Ẹ lọ ri tabi ki ẹ kọ'we si:—

Ọgbẹni Hudson Cole,
P.O. Box 477,
Eko.


## MR. A. KESSLER,

7, LABINJỌ LANE, WILLIAMS STREET, LAGOS.

## Pilsener Beer! Pilsener Beer!!

*One's thirst is quenched on taking a glassful*

"Lion Brewery Brand"

**Reduced to 32/- per case.**

*A TRIAL, FRIEND.*


Ọgbẹni na ni Ọti *Beer* tò yo-lù-wá ni tita ṣile mejilelọgbọn pere ni fun Apoti kọkan Igbadun mbẹ nibẹ ẹ jare. Ẹ rò tọ wò.

*Telegraphic Address* :—**BANK ANTHONY**

TOKUNBO, LAGOS.

Telephone No. L230, G.P.O. Box No. 300.

*Residence and Office 137 Tokunbo Street Lagos.*

Ọgbẹni A. BANK ANTHONY AND SONS jẹ Onișowo to nranșẹ ọja fun tita lati ilu ọba (*England*) wa. O si ma nfi ọja șọwọ sibẹ na pẹlu.

Diẹ ninu ọja ti o ma nra ni ilẹ yi ti o si ma nranșẹ ni wọnyi:—

Gẹdu, Rubber, Cocoa, Ekurọ, Epo. Obi, Igi Osun, Agbado, Iwo Malu, Awọ orișirișì.

Diẹ ninu awọn ọja ti o ma nranșẹ fun lati Ilu Ọba (*England*) wa fun tita ni ilu wa ni wọnyi. Așọ orișirișì, Akara Oyinbo, Ẹran oniyọ ati ọpọlọpọ nkan miran bi iru eyi ti o ta ni ilu wa ati Posi isinku iru eyi ti awọn ośișẹ wa ko le șe ni ilẹ wa.

Wo aworan ọkan yi, wa si ri daju pe awọn oșisẹ ilẹ wa ko le se iru rẹ.



Irohin ko to afojuba lọ si ile rẹ ni No. 137 Tokunbọ Street wa si ri daju pe ki ișe Iti asọdun o ni ti talaka o si ni ti Olowo eyiti a fi igi șe tabi eyiti o jẹ onidẹ (Brass)

Ẹ kọwe tabi ki ẹ ja waya si i a o si fi Posi ranșẹ si nyin nibikibi ninu ***Motor Transport.***

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| [illegible] a.m. | Christ Church | Rev. A. N. Cole |
| 6.30 p.m. | do. | „ J. Okuseyinde |
| 9 a.m. | —St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. A. W. Banfield |
| 4 p.m. | | Rev. J. A. Cole |
| 6.30 p.m. | | Rev. A. C. Onyeabo (of the Niger Mission) |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do. |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | ——— |
| 7 p.m. | do. | Rev. A. N. Cole |
| 10.30 a.m. | Ereko | „ E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | do |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | | „ S. A. Pearce |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Rev. S. A. Pearce |
| 7 p.m. | | „ E. E. Williams |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | do. | „ M. B. Newton |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. T. D. Shaw |
| 7 p.m. | do | „ J. T. A. White |
| 9 a.m. | Bethel | Bro. S. L. Akinoṣo |
| 6 30 p.m. | | „ A. Ọbadina |
| 9 a.m. | Zion | Bro. E. O. Peters |
| 6.30 p.m. | do. | „ Daniel Idowu |
| 10.30 a.m | African Methodist | Bro. Samuel Johnson |
| [illegible] 30 p.m. | | „ S. A. Fatolu |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. S. M. Phillips |
| [illegible].30 p.m. | | Rev. A. A. Puddicombe |
| [illegible] a.m. | Araromi (Baptist) | Rev. E. C. Alabi |
| [illegible] p.m. | | „ J. R. Williams |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | | |
|---|---|---|
| [illegible] a.m. | | Bro. Jẹariọgbe Tubi |
| [illegible].30 p.m. | | „ E. A. Ojo |

**BROTHERHOOD**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m. Ilupesi | Bro. S. A. Coleman Daniel |
| 7 p.m. | Pastor. A. Adedeji Iṣọla |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde

5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon; Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

Services at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

**CHURCH OF GOD**

22 Ọdunlami Street, Breaking Bread Open Air Service—Edwin Matthew & Wm. C. T. Terrell

---

MESSRS. J. R. THOMAS & SONS of Lisabi Hotel, Itori, beg to inform the public in general that they have been licensed by the Nigerian Railway to sell and serve refreshments etc. etc. to all passengers travelling on trains on up and down journey at Itori, Aro and Olokemeji Stations at very moderate prices. This venture has already been opened to them to the public at the aforesaid Stations any one travelling up to Ibadan and back and needing supply of any kind of refreshment should intimate us through the Station Masters Iddo to Ibandan, and *vice versa*.

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

**ALL STEVEDORING WORK**

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

**GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.**

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION*

TO

**S. I. M. Johnson,**

9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

## AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUYẸ

Fun Ile Ẹkọ.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. ALAWORAN | ... | 3d. |
| IWE ALAWORAN KINI | ... | 7d. |
| IWE ALAWORAN KEJI | ... | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sā kan nitori ogun Germani, ṣugbọn wọn tun de nisisiyi, a si le ri wọn ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S. ninu ilu yi tabi ẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ [illegible] ni awokọ inu wọn dara fun ọmọde to, ẹnit[illegible] ba dan a wo yio ri pe ọgbọn ẹniti o ti jẹ oluk[illegible] awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a fi to awọn iwe [illegible] lẹsẹsẹ, kiṣe iṣẹ *sare nbaja.*

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lọdọ oniwe ni ẹdin owo, 66, Ibadan Street, Ebute Mẹta.

## IWE ITAN T'O KẸ RIRI

Ọrẹ,

Lọ ra Iwe Itan ti Ibadan ati ti Ọyọ ni Ile-itawe ti *C.M.S.* nibi, ṣile meji meji ati sisisisi ni a nta ọkọkan.

Ọgbẹni Isaac Akiyẹle l'o ṣe Iwe Itan ti Ibadan Ẹ o si ri ọwọ rẹ ninu ti Ọyọ pẹlu.

## BOOKS! BOOKS!! BOOKS!!!

"History of Ibadan" and "History of Oyo" by ISAAC AKIYẸLE are on Sale at the C.M.S. Bookshop, Lagos, 2/- 6d. each.

JUST THINK OF THAT.



Persons desirous of selling or acquiring Houses or Land in the Colony of Lagos should communicate with

E. SOYEMI ALDER

who for many years has specialised in this class of Property. Sales effected by Public Auction or Private Treaty. Valuation for Mortgage or Probate carefully prepared. Loans arranged, Commissions reasonable.

☞ Please note address:—E. SOYEMI ALDER, Auctioneer, Valuer, etc., Owode (opposite the Law Courts) Tinubu Square, Lagos.

MR. ỌLABOYE LALẸYẸ.

Licensed Auctioneer and Commission Agent undertakes to advertise largely and to sell satisfactorily any goods, house or landed property for sale by public Auction. He is also prepared on request to proceed any where in Nigeria for valuing and selling purposes and he makes it a point of duty to effect quick payment for goods or property sold.

For arrangements please apply at his "Iwa Rere" Mart, Faji Market, near Phillips' Medicine Store, Lagos, or his residence No 20, Fagbayimu Street, Ebute Meta, selling days:—Monday, Wednesday and Friday from 9 o'clock a.m. till 5 p.m.

## ALASE LEATHER FACTORY.

### "ILE ALAWỌ."

Awọ ẹsẹ bata (*sole-leather*) ti a ṣe daradara, ti o lẹ ti o si pupa yo, ati Awọ Hausa ni orişirişi awọ, yala ni pupa, funfun, dudu, ofẽfe, ati orişi awọ miran ni a nta ni ọpọku ọvọku.




Bi o ba fẹ wa wo Ile Awọ nla yi, ti iru rẹ ko si ni *Nigeria*, bi bẽkọ kọwe ṣọwọ pẹlu owosi :—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawobata, Eko.


## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

## AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo oja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe nibi iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.


## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

MR. E. ADE. OGUNMOKUN,
*GENERAL TAILOR.*
47, Princes Street, Recently Established
*Try me and see.*

## WO'BI.

Ile ọwọ ti awọn Ajọsẹ ti a npe ni Ṣabu Ireti nbẹ ti 24 Ita Agarawu nibiti a gbe le ri orişirişi ṣẹrẹkẹ şin ati ọti-amu-nudun ra, si tun ni Ẹka Ṣabu kan ni 10 Ita Dosunmu nibiti ẹnikẹni le lọ ra ọja tirẹ ni ọpọku ọvọku.

Ọrẹ, kọwe si :—

Ọgbẹni SOLO. S. AJOSE
*Alabojuto.*
ni 10, Dosunmu Street,
EKO.

## ẸNYIN ONIṢOWO EKO.

Ẹ wa polowo Ọja nyin sinu *Eko Akete*, kolẹgbẹ ni ede Yoruba inu rẹ, o jare, o ši "ka-yin, wọbọ-wọbọ."

Ẹ tete sure wa, "Awure" nduro de nyin!!! Owo pọ ọ ni yio na ọ, ẹnikeji.


### "EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aṣoju wa :—

Ọgbẹni VINCE R. COLE.
Ajeniluja Stores, 109, Broad Street, LAGOS.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.